**23.** Atipe on ti ri i ni a wowo sanma ti o hàn gbangba.

وَلَقَدْ رَءَاهُ بِٱلْأُفُقِ ٱلْمُبِينِ ٢٣

**24.** Atipe on kò jẹ ẹniti o nṣe ãhun ọ̀rọ ti o pamọ.

وَمَا هُوَ عَلَى ٱلْغَيْبِ بِضَنِينٍ ٢٤

**25.** Atipe on kò iṣe ọ̀rọ èṣu ẹni ijuloko (egun).

وَمَا هُوَ بِقَوْلِ شَيْطَٰنٍ رَّجِيمٍ ٢٥

**26.** Nibo ni ẹnyin yio gba?

فَأَيْنَ تَذْهَبُونَ ٢٦

**27.** On kò jẹ nkankan bikoṣe iranti ti a fun gbogbo ẹda patapata.

إِنْ هُوَ إِلَّا ذِكْرٌ لِّلْعَٰلَمِينَ ٢٧

**28.** O wa fun ẹniti o ba fẹ lati duro dẽde ninu nyin.

لِمَن شَآءَ مِنكُمْ أَن يَسْتَقِيمَ ٢٨

**29.** Atipe ẹ kò le fẹ kinikan ayafi ti Ọlọhun Oluwa gbogbo ẹda ba fẹ.

وَمَا تَشَآءُونَ إِلَّآ أَن يَشَآءَ ٱللَّهُ رَبُّ ٱلْعَٰلَمِينَ ٢٩

## *(82) Suratul - Infitāri*

سُورَةُ الانفِطَار

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Nigbati sanma ba ya si meji.

إِذَا ٱلسَّمَآءُ ٱنفَطَرَتْ ١

**2.** Ati nigbati awọn irawọ ba njabọ.

وَإِذَا ٱلْكَوَاكِبُ ٱنتَثَرَتْ ٢

**3.** Ati nigbati awọn ibu odò ba di ohun ti o nṣan kakiri (ti gbogbo rẹ̀ ropọ̀).

وَإِذَا ٱلْبِحَارُ فُجِّرَتْ ٣

**4.** Ati nigbati awọn sãre ba nṣi silẹ̀.

وَإِذَا ٱلْقُبُورُ بُعْثِرَتْ ٤

**5.** Ẹmi kọ̃kan yio mọ ohun ti o ti ti ṣiwaju ati ohun ti o fi sẹhin.

عَلِمَتْ نَفْسٌ مَّا قَدَّمَتْ وَأَخَّرَتْ ٥

**6.** Irẹ enia kilo tan ọ jẹ si Oluwa rẹ Alabukun?

يَٰٓأَيُّهَا ٱلۡإِنسَٰنُ مَا غَرَّكَ بِرَبِّكَ ٱلۡكَرِيمِ ٦

**7.** Ẹniti O da ọ, ti O si ṣe ọ ni aṣepe, lẹhinna O ṣe awọn orike rẹ dọgba (O si tun gbe ọduro dãdã).

ٱلَّذِي خَلَقَكَ فَسَوَّىٰكَ فَعَدَلَكَ ٧

**8.** O si to eto aworan rẹ bi O ti fẹ.

فِيٓ أَيِّ صُورَةٖ مَّا شَآءَ رَكَّبَكَ ٨

**9.** Sibẹsibẹ ẹnyin pe (ọjọ) idajọ nirọ.

كَلَّا بَلۡ تُكَذِّبُونَ بِٱلدِّينِ ٩

**10.** Bẹni dajudaju awọn oluṣọ (iṣẹ nyin) wa lọdọ nyin.

وَإِنَّ عَلَيۡكُمۡ لَحَٰفِظِينَ ١٠

**11.** Awọn alakọsilẹ ti nwọn ni ibukun.

كِرَامٗا كَٰتِبِينَ ١١

**12.** Ti nwọn mọ ohun ti ẹ nṣe nisẹ.

يَعۡلَمُونَ مَا تَفۡعَلُونَ ١٢

**13.** Dajudaju awọn oniwa rere dajudaju nwọn yio wà ninu igbadun ti o ni ifaiyabalẹ̀.

إِنَّ ٱلۡأَبۡرَارَ لَفِي نَعِيمٖ ١٣

**14.** Dajudaju awọn oniwa buburu dajudaju nwọn yio wa ninu ina ti o njo.

وَإِنَّ ٱلۡفُجَّارَ لَفِي جَحِيمٖ ١٤

**15.** Nwọn o wọ inu rẹ̀ ni ọjọ ẹsan.

يَصۡلَوۡنَهَا يَوۡمَ ٱلدِّينِ ١٥

**16.** Nwọn kò si ni jade kuro ninu rẹ̀.

وَمَا هُمۡ عَنۡهَا بِغَآئِبِينَ ١٦

**17.** Kini yio jẹ ki o mọ riri ọjọ ẹsan nã?

وَمَآ أَدۡرَىٰكَ مَا يَوۡمُ ٱلدِّينِ ١٧

**18.** Lẹhinna kini o ma tun jẹ ki o mọ riri ọjọ ẹsan na?

ثُمَّ مَآ أَدۡرَىٰكَ مَا يَوۡمُ ٱلدِّينِ ١٨

**19.** Ọjọ ti ẹmi kan kò ni ni agbara kinikan fun ẹmi kan. Ti Ọlọhun nikan ni aṣẹ ni ọjọ na.

يَوْمَ لَا تَمْلِكُ نَفْسٌ لِّنَفْسٍ شَيْـًٔا ۖ وَالْأَمْرُ يَوْمَئِذٍ لِّلَّهِ ﴿١٩﴾

## *(83) Suratul - Mutọffifĩna*

سُورَةُ المُطَفِّفِينَ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ اللَّهِ الرَّحْمَٰنِ الرَّحِيمِ

**1.** Egbé ni fun awọn ẹniti o ndin oṣuwọn kù (Mutọffifina).

وَيْلٌ لِّلْمُطَفِّفِينَ ﴿١﴾

**2.** Awọn ẹniti o ṣe pe nigbati nwọn ba ma gba oṣuwọn (ti wọn) ni ọdọ awọn enia nwọn a gba (oṣuwọn nã) ni kikun.

الَّذِينَ إِذَا اكْتَالُوا عَلَى النَّاسِ يَسْتَوْفُونَ ﴿٢﴾

**3.** Ṣugbọn nigbati awọn ba fẹ wọn fun (enia) nwọn o din i kù (kò ni pe).

وَإِذَا كَالُوهُمْ أَو وَّزَنُوهُمْ يُخْسِرُونَ ﴿٣﴾

**4.** Awọn wọnyi nwọn kò wa mọ amọdaju ni pe a o gbe wọn dide.

أَلَا يَظُنُّ أُولَٰئِكَ أَنَّهُم مَّبْعُوثُونَ ﴿٤﴾

**5.** Ni ọjọ kan ti o tobi ni?

لِيَوْمٍ عَظِيمٍ ﴿٥﴾

**6.** Ọjọ ti awọn enia yio duro niwaju Oluwa gbogbo ẹda.

يَوْمَ يَقُومُ النَّاسُ لِرَبِّ الْعَالَمِينَ ﴿٦﴾

**7.** Agbẹdọ o, dajudaju akọlẹ̀ ti awọn ẹni buburu wa ninu «Sijiini».

كَلَّا إِنَّ كِتَابَ الْفُجَّارِ لَفِي سِجِّينٍ ﴿٧﴾

**8.** Kini yio mu ọ mọ amọdaju ohun ti o njẹ «Sijiini» nã?

وَمَا أَدْرَاكَ مَا سِجِّينٌ ﴿٨﴾

**9.** Akọlẹ̀ kan ti a ti lẹ̀ pa.

كِتَابٌ مَّرْقُومٌ ﴿٩﴾

**10.** Egbẽ ni ni ọjọ na fun awọn ti o pe ododo nirọ.

وَيْلٌ يَوْمَئِذٍ لِّلْمُكَذِّبِينَ ﴿١٠﴾